**Ijọ́ Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu**
**Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nàìjíríà**
**ÌSÌN OMI MÁNNÀ**
**Kókó Àdúrà – ÌWÒSÀN PÍPÉ (2)**

**Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 103:1-3:** Fi ibùkún fún Olúwa, ìwọ ọkàn mi, àti gbogbo ohun tí ó wà nínú mi, fi ibùkún fún orúkọ Rẹ̀ mímọ́. Fi ibùkún fún Olúwa, ìwọ ọkàn mi, má sì ṣe gbàgbé gbogbo ore Rẹ̀. Ẹnití Ó dárí gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ rẹ jì; ẹnití Ó sì tán gbogbo àrùn rẹ.

## Orin Ìyìn àti Ìjọ́sìn

1. Ẹ̀ṣẹ̀ ìyówù nínú ayé mi, tó n fa àìsàn fún mi, kú, ní orúkọ Jésù.
2. Mo lo ẹ̀jẹ̀ Jésù sí gbogbo àìsàn ìkọ̀kọ̀ nínú ayé mi, mo sì pàṣẹ kí wọ́n kú báyìí, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, dìde nínú agbára ìwòsàn Rẹ, kí O sì bẹ̀ mí wò, ní orúkọ Jésù.
4. Mo gbédè, mo sì lé jáde gbogbo iṣẹ́ ẹ̀mí ikú nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo pẹpẹ ìpọ́njú tí wọ́n yàn lòdì sí ayànmọ́ mi, gba iná, ní orúkọ Jésù.
6. Ègúnkègún tàbí májẹ̀mú-kí-májẹ̀mú, tí ó n ran ìkùnà lọ́wọ́ nínú ayé mi, fọ́ nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
7. Àwọn agbára tí wọ́n n rán ohun tó lòdì sínú ayé mi, gba ìparun lójijì, ní orúkọ Jésù.
8. Gbogbo òkè ìparun ọkàn, di yíyí kúrò nípa, ní orúkọ Jésù.
9. Mo mu ẹ̀jẹ̀ Jésù, mo sì pàṣẹ kí gbogbo gbòngbò ìpọ́njú nínú ayé mi gbẹ dànù, ní orúkọ Jésù.
10. Èmi kòní kú láti ipa ṣẹ̀ àìsàn ìyówù bíkòṣe yíyè, láti máa ròyìn àwọn iṣẹ́ Ọlọ́run àti ògo Rẹ̀ nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.

11. Gbogbo pẹpẹ òkùnkùn tí wọ́n gbékalẹ̀ lòdì sí aláfíà mi, wólulẹ̀ báyìí, ní orúkọ Jésù.
12. Mo dúró lòdì sí gbogbo ìránṣẹ́ èṣù tó n sọ̀rọ̀ ìdẹnukọ̀lẹ̀ nínú èrò sínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
13. Olúwa, jẹ́ kí iná Ẹ̀mí Mímọ́ jórun gbogbo irúgbìn búburú tó n ṣokùnfà ìdádúró t'ẹ̀mí sínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
14. Ọkùnrin tàbí obìnrin alágbára ìyówù, tó n rán ìpadàsẹ̀yìn sínú ayànmọ́ mi, kú lójijì, ní orúkọ Jésù.
15. Mo tú gbogbo ètò èṣù àti ti àwọn ìránṣẹ́ rẹ̀ ká, tí wọ́n fẹ́ fi ìpọ́njú-kí-ìpọ́njú dá ayànmọ́ mi dúró láyé, ní orúkọ Jésù.
16. Gbogbo ẹ̀mí ẹ̀rù àti àníyàn, tí wọ́n yàn láti ya igbàgbọ́ mi nínú Ọlọ́run lárọ, jáde báyìí nípa iná, ní orúkọ Jésù.
17. Gbogbo gbòngbò ìnira nínú ayé mi, gbẹ dànù, ní orúkọ Jésù.
18. Gbogbo óúnjẹ ibi tí ó n fa àìsàn ọkàn sínú ayé mi, mo pọ̀ ọ́ jáde báyìí, ní orúkọ Jésù.
19. Gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti fi ayé mi ṣòfò, ṣòfò dànù, ní orúkọ Jésù.
20. Gbogbo ìdíwọ́ t'ara àti t'ẹ̀mí sí àláfíà pípé mi, di mímú kúrò nípa iná, ní orúkọ Jésù.
21. A wò mí sàn nípa ìnà Jésù, ní orúkọ Jésù.